# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ?ỌRE AIYE. TẸNI GBOGBO LA WA

No 575 THURSDAY APRIL, 9 1964 (2D)


## Balewa Sare lọ si Kaduna

KADUNA:- Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria sare lọ si ọdọ Ala ba Alhaji Ahmadu Bello, O ori ẹgbẹ Ol?mi ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa lati lọ ṣe ibẹwo Alagbi na ni Kaduna ti iṣe Olu fun Ipinlẹ na.

Oniwe irohin wa Ejon'gboro ti o lọ si Ikẹja ko le ri Alhaji Balewa, nigbati yio fi de Ikẹja ọkọ ofurufu ti Balewa wọ ti lọ.

Ṣugbọn awọn oniwe irohin ti nwọn mọ nipa ọrọ oṣelu fi ye oniwe irohin wa wipe, nipa gbogbo awọn nkan ti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lọwọ bayi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lọ si Kaduna si.

A gbọ wipe Alhaji Tafawa Balewa lọ jiroro pẹlu Alagba Ahmadu Bello lori gbogbo rudurudu ti o nṣẹlẹ na, ati ọna ti Apapọ Ijọba le gbe ọrọ na gba.

Ko pẹ pupọ nigbati awọn enia tuka nibiti nwọn gbe nsọrọ ni alẹ, ni nwọn gbọ wipe Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ti tun pada de si Eko.

Ṣugbọn Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ko ba ẹnikankan sọrọ lori ohun ti o lọ ṣe ni Kaduna. Gẹgẹbi a ti wi siwaju, a lero pe awọn nkan ti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni o lọ Kaduna si.

# 'Ẹ FUN AWOLỌWỌ NI OMINIRA'

IBADAN:- Ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Oloye Richard Akinyẹmi, Akọwẹ Igbimọ ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) ninu Ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti o ti fi igbakan jẹ Minista Alamojuto eto awọn Ọba ati Ijoye, sọ ninu Ipade awọn oniwe irohin pe, ki nwọn fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifere ti o wa ni ọgba ẹwọn nisisiyi nibiti o nreti ẹjọ kotẹmilọrun ti o pe si ile ẹjọ giga ni ominira, nitoripe on ni o le mu alafia, ifẹ, isọkan ati ifaiyabalẹ padabọ si Ipinlẹ Iwọ Orun.

Oloye Akinyẹmi tun sọ wipe, gbogbo nkan ti di rudurudu ni Ipinlẹ yi nisisiyi ẹnikanṣoṣo ti o le mu gbogbo nkan na bọ wa si ipo gẹgẹbi o ti ṣe wa tẹlẹtẹlẹ ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu iranlọwọ awọn olotọ Igbakeji lati ma a ṣe iranlọwọ fun un.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

### AJAGA

Oloye na tun ṣe alaye wipe gbogbo awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun loni, egbe Afẹnifere ati ẹgbẹ Alakukọ ni gbogbo wọn nṣe, ẹgbẹ mejeeji yi, lo si le gba awọn enia Ipinlẹ yi ninu ajaga ati ẹbiti alapa ti o wolu awọn enia Ipinlẹ yi mọlẹ nisisiyi ti nwọn si nwa ọna lati gba jade."

Oloye Akinyẹmi ni "a ṣe ti obinrin ko ba danile ọkọ meji wo, ko ni mọ eyi ti o san ninu mejeeji" o ni gbogbo enia ni o mọ wipe "asiko ti Oloye Awolọwọ wa lori aga Oye, gbogbo nkan ko le koko bi oju ẹja bayi."

"Gbogbo enia ni o si mọ wipe asiko Awolọwọ tu awọn ni ara, ṣugbọn ko si ẹniti o mọ nigbati Awolọwọ wa nile, a fi nigbati o wa nibiti o wa nisisiyi ni gbogbo aiye to fura pe, ohun ti o sonu ni Mọṣalaṣi kọja bata Lemọmu"

Ni ipari ọrọ rẹ Oloye Akinyẹmi ṣe afikun ninu ọrọ rẹ wipe, gbogbo aiye, ki iṣe awọn enia Naijiria nikan, ni o nreti atipada ati abọde Oloye Awolọwọ.

### AWỌN ỌBA

Lẹhin eyi ni Oloye Richard Akinyẹmi wa kesi gbogbo awọn Ọba ati Ijoye Ipinlẹ yi, pe, "ki gbogbo wọn o dakun ijo keke ẹgbẹ oṣelu tuntun Ipinlẹ yi ti nwọn njo kakiri nitoripe, baba gbogbo aiye ni nwọn nṣe, ki i ṣe baba fun enia kanṣoṣo."

O tun ṣe alaye pe, laipẹyi ni awọn kan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ran awọn Ọba wa ri Alhaji Abubakaa nitori ọro kan.

Oloye na ni, "iwa ti awọn enia na hu lori ọrọ na jẹ iwa agabagebe nitoripe awọn Ọba na wa ni arin ilu, nwọn ko si ti ku, nisẹju wọn na ni, Ijọba Oloye


Wo oju ewe kẹfa


## ỌRỌ OLOTU

### Kini Fa Ija Igboro ?

GẸGẸBI o ti ṣe jẹ iṣẹ wa, awa na si ka a si ọranyan lati ma a fun awọn ara ilu ni imọran rere, eyiti yio ṣe ọpọlọpọ anfani fun awọn enia wa ti nwọn ba le gba imọran na ti nwọn si le fi ṣe iwahu, nitoripe ki a le ma a ṣi ara wa ni eti ati ki ama ba ṣe ṣi iwahu ni Ọlọrun fi fi wa ṣikẹ ara wa, inu wa yio si dun ti awọn alaṣẹ Ijọba tabi awọn ti eeku ida Ijọba wa ni ọwọ wọn, ti nwọn ko ba kọ eti ikun si imọran wa yi.

Gẹgẹbi gbogbo ẹnyin onkawe wa ti ṣe mọ wipe iwe Irohin Imọlẹ ko ??? mọ ẹgbẹ oṣelu kan, ti gbogbo awọn ẹgbẹ oṣelu ti o wa ni Naijiria ni awa oniwe Irohin Imọlẹ nṣe. O yẹ, o si tọ ki a le ma a sọ fun olukuluku enia lati mọ ohun ti o jẹ ẹtọ ti rẹ ati ẹtọ tiwa.

Awọn baba wa ni, "Bi ara ile ẹni ba njẹ kokoro buburu ti a ko ba tete sọ fun un, huruhuru rẹ ko ni jẹ ki a sun ni oru" Ki iṣe ohun iyi, ẹyẹ tabi ẹtọ fun ẹnikẹni larin ilu lati ma gba Alakoso Ijọba ni eti, tabi ki a ma ju moto rẹ ni oko ki a si ma ho iho yegede oju ti eke le e lori, bi o ti wu ki ole ri, ati iru iwa yowu ti o le hu.

Ṣugbọn owe awọn baba wa kan sọ pe, "Nwọn ni nwọn ko fẹ ọ ni ilu, o ni o fẹ da orin, ti o ba da orin tani yio gbe ?" Toto o, o ṣe bi owe, atipe "pa a ni oju ni ẹkini, pa a ni oju ẹkeji, bi oju na ko ba fọ, rabaraba rẹ ko le tan lara bọrọ."

O jẹ ohun iyalẹnu lati gbọ ohunti o ṣẹlẹ si Oloye Akintọla ati Oloye Fani—Kayọde ni Ilesha ninu ọsẹ ti o koja yi, pe nigbati awọn enia na wọ arin ilu, nṣe ni gbogbo awọn enia nkigbe "Ole! Ole !! le awọn enia na lori! Eyi ti lẹ tun s?n diẹ, eyiti o buru nibẹ ni igbati Oloye Akintọla nsọrọ ninu ile ti enikan si ju ogulutu si Oloye na! Ti o fi da ija Igboro silẹ, ti awọn ọlọpa mu enia mẹtadinlogun ti nwọn wa ni ile-ẹjọ nisisiyi.

Ni tootọ, ọran na wa ni ọdọ awọn ọlọpa, bi nwọn ba si ti pari ọran na si, ẹ o ma a gbọ; o dabi ẹnipe awọn ara Ipinlẹ Iwọ Orun ko fẹ Oloye Akintọla gẹgẹbi Alakoso Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tabi nwọn ko feran ẹgbẹ Oṣelu tuntun ti Oloye na dasilẹ, nwọn si nfi ifẹ ọkan wọn han Oloye na, eyiti iru rẹ ko ṣẹlẹ ri ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Bakanna ewẹ, ni iru nkan bayi ṣẹlẹ nigbati Oloye Akintọla lọ si Ijẹbu ninu ọdun ti o kọja yi, nigbati Oloye na de Ijẹbu a gbọ wipe awọn ọmọ Ile-ẹkọ oju Oloye na ni oko ati ogulutu. Awọn Ọlọpa mu awọn ọmọ Ile-ẹkọ na, ṣugbọn adajọ da wọn silẹ.


Wo Oju Ewe Kẹfa

# Ọrọ 'Yoruba Ronu' Ode Oni

**Lati Ọwọ S. O. Jaiye**

Jakejado Ilẹ Naijiria ni a tun gbe ede titi n yi de ilẹ wa. Ti a ba ni ki enia ronu–Enia ni lati bi ara rẹ lere wipe kini de ti ẹnikan nwi fun on pe ki on ronu ?

Ti a ba ni ọ m ọ de ni ile ti ọ m ọ na ba nṣaba ma a hu awọn iwa ti ko dara to, ti a si nkilọ fun, a le wi fun ọmọ na wipe ki o lọ ronu lori tabi ni ọna rẹ ti o yẹ fun iyipada si ọna rere.

Bakanna a le ni ọrẹ ti iwa rẹ ko ba ti ẹni mu tabi ti ọrẹ na ba jẹ janduku enia ti a fẹ ki o yi pada ti ko si fẹ yi pada, ao sọ fun pe ki o lọ ronu rẹ ki o si yi pada si rere. Ọna orişirişi ni a ma lo ede yi fun ara ati ojulumọ.

ARA GALATIA

Ọrọ ti o ba ti mu ede yi wa fi han gbangba pe enia ti nkuna ninu ọna rẹ to yẹ fun atunşe. Bayi ni mo ri lilo ede ronu yi si.

Şugbọn ohun to jẹ mi logun ninu lilo ede yi loni ni pe, ọna ti awọn to nlo ede na dabi ẹnipe awọn ni ko ronu lori ede na rara. Awọn enia Yoruba ki şe ara Galatia rara. Yoruba ki si şe oponu.



Ọgbẹni S O. JAIYE

Ohun to fa sababi ni ẹniti o ba aja rin yio jẹ igbẹ, ti ojo enia ba jẹ aşaju ogun laisi aniani ọta yo şegun wọn laipẹ.

MOYANMOYAN

Awọn ajẹ ezbodo wa ni kunra aşaju ilẹ Yoruba ni o ko moyanmoyan wa ba enia ile yi. Ko yẹ rara lati ma da aşa na pe ki Yoruba ronu.

Jẹje ni awọn ẹni rere ilẹ Yoruba joko ti awọn kan da ẹgbẹ ọdọ Naijiria silẹ (NYM) nigbati o şe, Ẹgbẹ Afẹnifere de Yoruba tun gba awọn ẹgbẹ yi tọwọtẹsẹ şugbọn awọn aşaju kan lo mu wahala ba ẹgbẹ yi.

Loni a tun gbọ wipe Ẹgbẹ Dẹmọ lo tun ni ode. Lasiko yi ni Yoruba yo wa ma a ronu.

Jowọ ẹnyin ara, ẹnyin ara ilu mi, ironu kan ko ba Yoruba rara. Ẹnyin aşaju ilẹ Yoruba ni ki ẹ ma ronu ninu ara nyin fun gbogbo idarudapọ ti ẹ nda sile lojojumọ.

Ẹ lọ ronu fun awọn ẹsan ti yo wa ba nyin lode aiye fun iru iwa ti ẹ nhu larin nyin iba şe rere tabi buburu.

Ẹlọ ronu awọn ibi ti ẹ hu si awọn Ọmọnikeji nyin. Ọjọ ki pẹ titi ki o ma ku ọla. Bakanna ibi ki wa ki o ma ni ẹsan.

OKELE ONJẸ

O jẹ iyanu pe ọpọlọpọ to ba nhu iwa ko mọ pe ẹnikan nwo awọn. O yẹ ki awọn ti o npe ara wọn ni aşaju mọ pe nwọn ki şe ọbọ Ọbọ papa na ma nronu ninu ọna rẹ ninu igbo ti ko ba şe pe nwọn nronu ni ọdẹ ibati pa gbogbo wọn rẹ ni ọjọ kan.

Awọn to nhu iwa aitọ larin ilẹ Yoruba lo mu moyanmoyan wa ba orilẹ ede yi. Nigbati awọn alaironu ko ara wọn jọ pọ tan sibi okunkun aiye wọn.

Nwọn bẹrẹ si şọ wipe Yoruba ronu. Ko si ẹtẹ kan to ba Yoruba bi ko şe awọn ti okele onjẹ aiye ngbe kiri.

Yoruba ninu ọgbọn wọn şọ pe Ika ko sọ pe ki enia ma bimọ bẹni iwa ibajẹ ko şọ pe ki a ma ni owo lọwọ şugbọn ohun to ga ju ninu gbogbo rẹ ni ọjọ ati sun. Eyi ni ọjọ ikẹhin tabi ọjọ iku.

Nigbogbo Naijria loni ko si ibi ti nwọn ko fi ọwọ wọ awọn ọba, nwọn a fi ilẹ Yoruba to nyọ ọba nwọn bi ẹni yọ jiga lẹsẹ.

Nwọn wi tai wi nwọn ni ki Yoruba lọ ronu fun iwa ibaje ti o nti ọwọ awọn papa jade fun ibajẹ aiye oni yi.

Şe gafara fun mi iwọ asaju ti o ba nlọ ede yi lo ba ọdọfin inu rẹ şe apero iru iwa to nhu fun igbegasoke Ilẹ Yoruba wa yi.

Ni temi mo mọ pe Yoruba ko dẹkun ironu lori iwa ododo iwa atunşe gbogbo to yẹ idile iwa to ni ọwọ iyi ati ẹyẹ ninu itẹriba fun ẹniti ọla nşe tirẹ.

Wo Oju Ewe Kẹfa

# YẸYẸNATU

## Oni Yẹyẹ Eko

Yẹyẹnatu:- Olotu, ẹru gbogbo enia lo tun ba yin ni

Olotu:- Ẹru tani mo sọ pe o nba mi tẹlẹ?

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin ọmọ ẹgbẹ ọlọwọ

Olotu:- Tani sọ fun ọ pe, ọmọ ẹgbẹ ọlọwọ ni on?

Yẹyẹnatu:- Tabi ẹru temi na nba yin.

Olotu:- Gbe ẹnu rẹ sọhun o jare

Yẹyẹnatu: Ko ya m lẹnu, şe gbogbo ẹni ti i ẹ ba nbẹru na lẹ nsọ pe ko ko ara rẹ kuro lọna fun yin

Olotu:- O jẹ tọrọ idariji.

Yẹyẹnatu:- Şe lọdọ yin tabi lọdọ tani?

Olotu:- Tani a le kuro lọna

Yẹyẹnatu:- Ogunde nkọ?

Olotu:- Iyẹn yatọ

Yẹyẹnatu:- Iyatọ wo? şe ntoripe o ni Yoruba ronu lẹ şe sọ pe ko gbọdọ de ile baba rẹ mọ

Olotu:- On na şe sọ pe ki yoruba ronu

Yẹyẹnatu:- Ha ko tete ye Ogunde ni

Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu:- Ko mọ pe ọjọ ti Yoruba ba ronu ni Ijọba Akintọla yio fọ

Olotu:- Bawo ni yẹn?

Yẹyẹnatu:- Şe bi a ba ronu gbogbo awawi Akintọla ko ni jẹ kinikan. Şugbọn o yẹ ki Ogunde na mọpe inu Akintọla ko le dun si ohun ti on wi.

Olotu:- Şebi 'Yoruba ronu' na ni ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin si nke kiri tabi ọrọ kọ ni awọn mejeji?

Yẹyẹnatu- Ha-ha-ha! ohun to da wọn pọ ti yà wọn. Ọgbọn agbọnju Akintọla to da gbogbo rẹ si lo da ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin silẹ ntori ati rẹhin ọta, ọgbọn agbọnju na lo tun ya Akintọla ati ọmọ Ọlọfin.

Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu:- Şe ẹnyin mọ pe baba Dele ki i fẹ fi oye silẹ bi o ba dori oye, o si mọ pe bi on ba nba ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin rẹ, nwọn yio fi Majẹkodun şoga on, lo ba sare da NNDP silẹ laiba wọn roo

Olotu:- O fẹ sọ fun mi pe ki işe Akintọla ati ẹgbẹ ọmọ Ọlẹfin lo da ẹgbẹ yẹn si

Yẹyẹnatu:- Emi na kọkọ ro pe nwọn jọ da silẹ ni şugbọn nigbati mo fi i m u fiolẹ titi mo gbọ daju pe oloyipo ni

Olotu:- O maşe o

Yẹyẹnatu: Iyẹn ya nyin lẹnu ni. Tani ko ti mọ pe, ibiti o ja si yẹn ni yio ja si? Ẹnyin ẹ ma wo igbẹhin ọrẹ aja ati ẹkun ti on ati Fani-Kayọde nşe

Olotu:- Şugbọn şọra rẹ pẹlu gbogbo ohun ti o nsọ yi ki nwọn ma le wa ni Iwọ Orun bi nwọn şe le Ogunde o

Yẹyẹnatu:- Hẹ, igbẹhin alaşeju lo şoro, ẹ le ọtun nilẹ baba, ẹ le osi nilẹ ba igbati o ba pẹ şe ẹri ẹni le ẹnyin na

Olotu:- Kọjọ yen tode nkọ

Yẹyẹnatu:- Iyẹn ni nkan

Olotu:- Adura ni ki a ma gba şe Akintọla ni ẹgbẹ ọlọwọ awọn ko şẹhin Olodumare

Yẹyẹnatu:- Kini nşẹhin Olodumare tẹlẹ ?

Gbogbo iwa buruku ti nlọ paapa, tani ko mọ pe Ọlọrun nri ohun gbogbo. Osi le şe ohun gbogbo.

Olotu:- O ma ti di alufa

Yẹyẹnatu:- Ewo ni akoko yi ko ni sọ wa da? Oo ri Akintọla to sọ ẹrọ gbohungbohun di ẹro ike de N N D.P, oni'e ọlọna dẹniti npolowo ẹgbẹ bi ẹni polowo ẹkọ

Olotu:- ọwọ bọrọ ko şe gbọmọ lọwọ ekurọ

Yẹyẹnatu:- Oye mi, o jare o digba kan na.

# Aṣoju Ijọba Gẹẹsi Bẹrẹ Ayẹwọ Ilẹ Naijiria

EKO:— Lẹnulọlọyi ni Aṣoju fun ile Gẹẹsi ni ilẹ Naijiria bẹrẹ abẹwo akọkọ lati igbati o ti de si ilẹ Naijiria lati ilu Gẹẹsi. Ọlọla Francis Cumming-Bruce ati Iya afin Cumming-Bruce fi ilu Eko silẹ ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ keji oṣu yi fun irin rẹ akọkọ si iha Ila Orun Naijiria Ọlọla Cumming Bruce ati Iya afin Cumming-Bruce yio ṣe abẹwo Olotu Ijọba Ipinlẹ na ati awọn minista re pẹlu yio tun ṣe abẹw awọn ọpọlọpọ enia ilẹ na pẹlu awọn enia lati ilẹ Gẹẹsi ti o tun wa ni Ipinlẹ na.

Ọlọla Francis Iyaafin Cumming-Bruce ti wa ni Enugu lati ọjọ keji ọjọ kerin oṣu yi gẹgẹ bi alejo fun Gomina Ipinlẹ na Ọlọla Francis Ibiam ati Iyaafin Ibiam.

Ọlọla Francis ati Iyaafin Cumming-Bruce si jẹ ase kan ti Olotu Ijọba Ipinlẹ na pe fun u o si tun ba awọn Minista Ipinlẹ na sọrọ.

Igbakeji Asoju ilẹ Gẹẹsi ni Ila Orun Naijiria Ọgbẹni R. C. Chisholm si tun fi ase nla rẹpẹtẹ da Ọlọla Francis ati Iyaafin Cumming-Bruce lọla o si tun ba awọn oṣiṣẹ ti ile iṣẹ ti igbakeji Aṣoju fun ile Gẹẹsi ni Ipinlẹ na sọrọ.

Ọlọla Francis ati Iyaafin Cumming-Bruce si nada si Eko ni ọjọ kerin oṣu yi.

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kefa osu yi, Ọlọla Francis ati Iyaafin Cumming-Bruce si fi Eko silẹ fun irin ajo wọn si Ipinlẹ Ariwa Naijiria ni Kaduna fun ipe ti Olotu Ipinlẹ na Ọlọla Ahmadu Bello pe.

---

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Iṣọra di ọwọ rẹ nipa ọrọ ija kan to pari rẹ, nitoripe agbara ija ko iti si fun ọ nisisiyi, ki o ṣe bi o ti mọ.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Gbogbo eto ti o ngbero lati ṣe, le jabọ silẹ, ki o tọju ọrẹ tituṉ ti o ṣẹṣẹ ni, esanri le ba ọ jade ipo ti yio bo gbogbo eto re jẹ.

ARIES (Marh 21 - April) Ṣe ohun ti o wa lọkan lati ṣe kiakia ki ifẹ ohun na to kuro lọkan rẹ, gbo bo awọn oku ọrun lo ngbadura fun ọ.

TAURUS (April 21-May 20) Ọjọ oni dara fun ọ lati ṣe faaji to jẹpe are ko ni mu ọ Maṣe ronu pupọ ki gbogbo awọn ohun ti o ngbero lati ṣe ba bọsi oju rẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Bi o ko ba le ko ara re ni ijanu awọn oku ọrun yio ṣe idalọwọkọ pupọ fun ọ ṣọra re nitori ewu mbẹ fun ọ aisan ati amọdi mbọ.

CANCER (Jun 22- July 23) Ṣọra rẹ nitori amodi mbẹ ni ago ara rẹ ori rẹ ama pe ni akoko owuro, ṣugbọn ṣọra rẹ nipa inakuna.

LEO (July.24-Aug.22) O dara fun ọ, lati tete ma sun ni akoko yi, ki o si le ma teteji. Ṣọra ki o maṣa nawo baranda.

VIRGO (Aug.23-Sep 22) Edekoyede yo wa larin iwọ ati awọn ojulumọ rẹ, ṣugbọn jẹki ibinu rẹ mọ niwọn awọn ohun kan ti o ngbero lati ṣe bọsi deedee loni.

LIBRA (Sept.24-Oct23) Jẹki ori pe, owo yio pọ ni ọwọ rẹ loni. Maṣe fi iṣẹ rẹ ere, ki o si ma wa ilọsiwaju fun awọn ti o nfẹ ilọsiwaju rẹ.

SCORPIO (Oct.24-Nov.22) Mura ki o si rin irin ajo, nitori ki alafia ba le to fun ọ mọse fi ara rẹ sere, nitori pe ara rẹ nfẹ amojuto.

SAQITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ẹbun rẹ lati ọrun wa nipe ki awọn oku ọrun ma ni fẹ rẹ, ohun kohun ti o ba si dimu ki o ma lọ deedee.

CAPRICORN (Dec 23 - Jan. 21) Ohun ti o ba ṣe akiyesi pe, o lewu maṣeda ara rẹ si le baananani tirẹ papa a jẹ.

---


## EGBOGI JEDIJEDI

FUN EGBOGI



## "CYCLOVE"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bere bakana. Orişirişi Jedijẹdi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ. ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣelu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adi fun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewe ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVE" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ a ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹ dijẹdi na pata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogid taata gboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba


---


## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JE RI O, OLUWA MO JE IPE RE

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARE MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiyé ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin.

## "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati vio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SITTU STREET
Ibadan


---

## Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ lojojumọ

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORỌ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 575 THURSDAY, APRIL 9, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Gbogbo Enia

Lehinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọle Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati odun meje (1957) sehin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn eniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba,


16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.


# AWỌN ỌBA IPINLẸ IWỌ ORUN LỌ RI BALEWA

IBADAN:- diẹ ninu awọn ọba ninu ile Igbimọ lọbalọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lo ri Olotu Apapọ ile Naijiria Alhaji Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa fuu iyasọtọ ti o nṣẹlẹ ni ọpọlọpọ awọn ile iṣẹ ti ilẹ Naijiria papa julọ ni ile iṣẹ ti Reluwe.

Ọba Fẹwọgboyẹ, Osemawe ti Ondo ti o si tun jẹ Olotu ile igbimọ Lọbalọba ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lo si jẹ asiwaju awọn Ọba ti wọn wa lati wa ri Ọlọla Abubakar fun ọrọ. Awọn Ọba na si fi Ibadan silẹ gẹgẹ bi wọn ṣe nkuro ni ile igbimọ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa osu yi, nig ati wọn sọ ọrọ le iwa iyara sọtọ ti o nṣẹlẹ si awọn ọmọ Yoruba ti o wa ninu ọpọlọpọ ile iṣẹ ati ifun onirunru ipo ti o yẹ, ki awọn ọmọ Yoruba wa ni ilẹ Naijiria.

Awọn Ọba ati Ijoye si paṣẹ ni ile Igbimọ wọn lati le ran awọn ikọ ninu awọn Ọba ati Ijọba lọ si ọdọ Olotu Apapọ ilẹ Naijiria nips nkan to le fa jamba wa fun iṣọkan ilẹ Naijiria.

Ẹni to si gbe ọrọ na dide ninu ile Igbimọ aṣofin ti awọn lọbalọba ni Ewi ti Ado-Ekiti Ọba Aladesanmi keji ti o si sọ ninu ọrọ rẹ pe ọpọlọpọ iya ati iyasọtọ ni wọn si fi nkan awọn ọmọ ilẹ Yoruba to wa ni ọpọlọpọ ile iṣẹ ti Naijiria. Ọba Adesanmi si tun sọ ninu rẹ pe eleyi si fi han gedegbe pe ninu iwe kan ti o jade ni ọsẹ ti o kọja fi han pe iru iwa buburu bayi si nṣẹlẹ ni ile iṣẹ ti Reluwe.

Ọba Aladesanmi si tun sọ sii pe inu on ko dun rara si iru iwa bayi nigbati on ri ka ninu awọn iwe kan to jade ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi papa julọ iru nkan ti o ṣẹlẹ si Ọgbẹni F. M. Alade ti o jẹ igbakeji Ọga agba ni ile iṣẹ Reluwe ti nwọn si daduro lojiji lẹnu iṣẹ.

Ẹni to tun gbe Ọba na lẹsẹ ninu ọrọ rẹ ni Ọba M. S. Awolesi Akarigbo ti Ijebu Rẹmọ ti o tun jẹ Olori ile Igbimọ lọbalọba ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si tun sọ ninu ọrọ rẹ pẹlu pe iru iwa eleyi si jẹ nkan to lewu pupọ ati pe awọn Ọba si ngbadura lati le jẹ ki iru iwa iyasọtọ le jẹ nkan ti yio parẹ patapata ni Naijiria.


Lati Oju Ewe Keji


Iwa itanju ẹni ẹhin dada nitori nwọn mọ pe awọn ni nwọn yo fi ẹhin silẹ fun lẹhin ọla.

Yoruba tun sọ pe opa agbelepa ti ẹhin tojn. Gbogbo awọn oro ati imọ oye wọnyi ni Yoruba mọ fun itọsi ọna wọn.

Ṣugbọn loni ko ri bẹ nitori awọn olotu Yoruba Ronu ti ba ilẹiẹ gẹgẹ bi ọrọ Alaṣe Alhaji Abubakar to wipe. "awọn to wa lode ilu ede wọn ye ara wọn ju ti awọn ti a npe ni asaju ninu ile ofin ati Igbimọ.

Nitori na Yoruba ki ṣe ara Gal-tia-Ọmọluwabi ni wọn nitori na mu ọrọ ede miran sọ.

O digba o.

## 'Ẹ Fun Awolọwọ Ni Ominira'


Lati Oju Ewe Kini


Akintọla ṣe da, ọjọgbọn ọmọwe iyenuga duro ni Unifasiti Ifẹ

Bakanna ni Ijọba da irinwo (400) awọn ọmọ Ile ẹkọ Ilesha duro nitoripe nwọn ko le Oloye Akintọla loro.

Ni arin ilu ni ẹ wa nigbati Ijọba gba Oye lọwọ Oloye Kẹlawọle Balogun ti iṣe igbakeji akọwe ẹgbẹ ọmọ Olọfin ti Ijọba si tun da duro ni Ile Igbimọ awọn Ọba.

Ni arin ilu ni ẹ wa nigbati Ijọba da Oloye I. O. Dina dure lẹnu iṣẹ, kini ẹnyin ọba ṣe si oran na titi di isisiyi? tabi tani ẹ lọ ri, tabi ọmọ Yoruba kọ ni gbogbo awọn ti mo ka silẹ wọnyi?"

Ti o ba jẹ wipe, ẹnyin Ọba ati Ijoye ko ba ni huwa agabagebe, ti ẹ si gba wipe baba gbogbo ọmọ Yoruba ni ẹ ṣe, kini ẹ ṣe si ọrọ na nigbati ẹ gbọ?"

Oloye Akinyẹmi wa kilọ fun awọn ọba pe, ẹ maṣe jẹki awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan o ma a yi nyin bi yimiyimi kakiri arin ilu nitori ifẹ ọkan wọn.

Ni ipari, Oloye Akinyẹmi ṣe alaye pe, awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakuko ti nṣe ipade pupọ ninu Ile Oloye Awolọwọ ni Oke-Ado, o wa pari ọrọ rẹ pe, ni oṣu kẹjọ ọdun 1965, ẹgbẹ A. G ati N. C. N. C. ni yio jijọ ma a ṣe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

## Kini Fa Ija Igboro?


Lati Oju Ewe Kini


Bi ẹnyin onkawe wa ko ba gbagbe, eo niran pe nigbati Oloye Akintọla lọ si Ilaro, rogbodiyan bẹ silẹ ni Ilaro, agbọ wipe, Oloye Akintọla ti paṣẹ pe ki nwọn ti Teṣan awọn Ọlọpa Ilaro nitori ọrọ na, awọn Ọlọpa na ko si ri owo-osu wọn gba.

Ni ẹgbẹ keji ewe, Ijọba ti ṣe ofin wipe ko gbọdọ si ipade gbangba ode ati iwode, ṣugbọn Oloye Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ nṣe ipade gbangba ode ati iwọde. Awa oniwe Irohin Imọlẹ ko lodi si eyi, nitoripe ọwọ wọn ni eeku ida Ijọba wa, ṣugbọn a fẹ ki awọn Ọlọpa o ma a ṣe iṣẹ wọn, ki wọn o si ri wipe ẹnikan ko ṣe ipade ti o le da ija igboro silẹ.

Ohun ti nlọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun lọwọ bayi fẹ amojuto, o si dabi, (a ko sọ pe bẹ lo ri o) awọn ara ilu ko fẹ ẹniti o wa ni asiwaju won.

Awa Oniwe Irohin Imọlẹ kesi Apapọ Ijọba ki nwọn tete mojuto ọran na, nitoripe ohunti o ba ba oju, o ba imu pẹlu.

Ọmọluwabi ati enia rere ni awọn ọmọ Ijẹsha, ṣugbọn ohun ti wọn ba sọ pe awọn ko ṣe, bi ọrun yio ba wo lalẹ, nwọn ko ni ṣe ohun na.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street P. O Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) Bariga Lagos (9/4/64)